IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 716 WEDNESDAY JUNE 10, 1964 (2D)

## Fani-Kayode Fara K'orin!

LONDONU:- Oro di pentuka nigbati Oloye Fani-Kayode, Minista Alamojuto eto Ijoba Ibile ati Igbakeji Alakoso Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria de Ebute oko ofurufu ti awon enia kan si lo kolu Oloye na bi ejo aije ni deede agogo mejo ale ana ojo Isegun ti ise ojo kerin osu yi.

Irohin fi ye wa pe, Oloye Fani-Kayode ati awon alase Asoju Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria ni ilu Oyinbo jijo nlo si Ebute Oko Ofurufu ni ija na ba se sile larin awon enia mejeji

Irohin na se afikun pe lati bi ojo meta ti Oloye Fani-Kayode ti de si ilu Oyinbo lati lo se eto kan fun Ijoba Ipinle Iwo Orun, ni awon enia na ti nwa a kakiri lati na a, sugbon nwon ko ri aye.

Nigbati o si di ale ana ni nwon to ri aye ti owo won si te Oloye na bi nwon ti se nfe.

Lesekese ni awon olopa de ti nwon si gba Oloye na sile lowo awon enia na. Awon Olopa nse Iwadi oro na lowo, bi a ba si tun ridi oro na si, e o maa gbo ninu iwe irohin wa ni ola.



Oloye Fani-Kayode

# AWON OSISE TAKU MO IJOBA L'OWO!

EKO:— Ni deede agogo mefa irole ana ni gbogbo awon osise se ipade gbogbo-gbo o ti gbogbo won si so pe awon ko faramo oro ti Ijoba so pe ki awon pada si enu ise awon larin wakati mejdinladota eyiti yio pari ni owuro yi

Awon Asiwaju Osise na se alaye fun gbogbo awon Osise pe, "Ijoba nhale ni" ti nwon yara tete pada si enu ise awon.

Awon Osise na so pe awon setan lati pada si enu ise won ti Ijoba ba ti gba lati fi owo kun owo osu awon, ki nwon si tun san owo -oya osu mesan ti igbimo Morgan so pe ki Ijoba san.

Awon osise na ni, ti Ijoba ba ti pinnu pe awon setan lati san owo na fun awon, awon paapa na setan lati pada si enu ise awon laisi iyonu.

Onirohin wa kan ran wa leti pe, ni ijeta ni Alhaji Abukar Tafawa Balewa Alakoso Apapo Ijoba Naijiria ti so fun gbogbo awon osise pe ki nwon tete pada si enu ise kia-kia.



Alhaji Adebola

Bi e ba bere ise nyin, ki e ma a wa a bere fun ohunti e ba fe sugbon Ijoba mi setan lati san owo osu repete fun osise kan.

"Lati bi ojo mesan ti e da ise sile yi, Ijoba ti padanu owo gobgi ti ko se fi enu so"

"Sugbon bi enyin Osise



Ogboni OBANDE
Minista, Eto Ise

ba ko, ti e ko si gbo imoran mi iji, ti e si ko eti ikun si i, Ijoba mi yio lo ida ati ase ti o wa lowo mi, lati fi da seria fun nyin.

"Gbogbo ohunti Ijoba ti nfi ara da bo lati bi Ose meji yi pelu enyin Osise, o ti wa de ori gongo, Ijoba mi ko tun le faradaa lo ju bayi lo mo"

"Bi Ijoba ba san owo ti e mbere yi fun nyin, awon onisowo ko ni le san owo na, nwon si le da awon enia die duro lenu ise, sugbon Ijoba ko fe ki awon onisowo da enikan duro bi ko sepe ki nwon ma a gba kun awon osise won atipe Ijoba ko ni owo lowo lati san fun enyin osise, owo ti tan lapo Ijoba."

Sugbon ninu Ipade ti awon osise se ni ana, nwon se alaye pe, gbogbo awon ile ise kakiri Orile ede yi, awon Oselu wa ni nwon da gbogbo re sile

Nwon tun se alaye siwaju pe, eyiti ki ise pe awon lo da sile, awon ni nwon je Alaga ile ise na, nitori idi

.eyi, ni nwon se ntenu ma a pe, "awon Onisowo ko ni le san owo fun awon osise won".

Ogbeni Michael Imoudu se alaye pe "ko si owo lowo Ijoba, sugbon Ijoba nsan ponun medogun (£15) losu fun awon aja Oyinbo ti awon olopa fi ngmu ole."

Igbimo egbe awon Osise so ni Eko lana pe, "Apapo Ijoba ko se Olotito si ise won, bi o ba je wipe, nitoto ni Ijoba ko ni Owo lowo, kini se ti Ijoba nsan (£333 : 10/-) ni Osu kan fun awon Oga kan ni enu ise ?"

Awon osise na pe, "oye ki Ijoba ge owo osu iru awon enia ti nwon ngba egbaa meji ponun ( £4,000 ) ni odun kan lenu ise, nigbati awon osise ti o nse ise gan an ngba ponun mejo ( £8 ) losu kan

Awon asiwaju egbe osise na ni awon ngbo wipe awon kan ti npe gbogbo awon osise won nwon si nhale mo won pe "Bi e ko ba bere ise nyin ni ola, gbogbo nyin ni ao da duro ti ao si gba awon elomiran ropo nyin."



Oloye J. M. Johnson



Alhaji Abubakar Balewa

Awon asiwaju egbe osise na se alaye pelu idanil ju pe ki awon osise na mase jaya "Ihale ni awon alase ise na nse. Nwon ko gbodo da awon osise kan duro eyi si wa ninu akosile ofin iselu orile ede yi.



Gogo C... ...ico

Awon Obiarin oloja ti fi owo ku owo oja won loja, owo moto lati Eko si Ibadan ati Abeokuta ti tun fi owo kun owo moto.

Awon osise si tun taku mo Ijoba lowo pe awon ko ni pada si enu ise afi ti Ijoba ba san ekunwo na fun awon.

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU (Apa 16)

## Lati Ọwọ J. O. Shoyinka

Enia lo nfi enia lọba, enia lo si tun nrọ ọba loye. Lorukọ mi ati ti awọn ẹlẹgbẹ mi a rọ ọ loye alaga wa lati oni lọ ati titi lai. Gbogbo wọn ṣe Amin" Ohun ti owi, agbọ ni, ako gba, lọjọ oni o, mo wi fun ọ. Aki ri ajẹku oro bi Oluwa ko ṣe ẹru ru, eti awọn ọmọ onilogbo li ao fi da ila,Itan wọn kandu kandu lori oreṣi agbari wọn ṣe fifi mu omi gbun-gbun-gbun ni

Agbara ti o ba ni ki o sa ki ari ṣugbọn ki nto pari ọrọ rmi, mo fẹ ki o mọ daju pe a f'emi, Af'emi ni kiniun igbani ti nke ri, sugbọn nigbati ọdẹ ta a l'ọfa, o nke pe A FEMI, AF'ENIA, nitorina enia kan ki i jẹ awa de bi o ti lagbara ni ọrun alakeji, ni awa na lagbara ni ile aiye, ko to lo agbara rẹ wa de ajule rẹ lọrun lọhun Awọn ọmọ Onilogbo wa ninu irora dide lọwọ ati lẹsẹ, oju wọn npọn ko o bi ẹjo ọka, itọ ẹnu wọn ti gbẹ, nwọn ko si lagbara lati kepe Ayunọrunbọ fun iranlọwọ nitoripe agbede—meji ọrun ati aiye ni nwọn wa, nwọn nwo su u.

Pa wọn giri ọjọ n l ọ, awọn alaṣẹ ti nbere ohun ti nwọn ni, ki ẹran ba to o jẹ? Kini alapata gbọ bayi si–o fa ida re yọ, o fẹ k ọ kọ dunbu Ige.

Awọn Ajẹ bo ilẹ ti nwọn gbe nṣe ni ipade yi sikan, nwọn to ẹgbẹgbẹrun–ọnaẹgbẹrun, A g o g o omiran pupa, omiran dudu, omiran jẹ ofefe, gbogbo wọn npariwo yanmu.

Ayunọrunbọ paṣẹ pe ki wọn kọkọ mu ẹjẹ alapata tan, ki o to wi bẹ ẹ, wọn ti mu ẹ j ẹ alapata g b ẹ k-dere.

O ṣubu lulẹ, o ku. I r u bi awọn Igbimọ tobẹ gẹ ẹ, nwọn y ọ kunmọ, nwọn nlu awọn ẹiyẹ yi pa, nwọn ba lu ikan pa, igba ẹiyẹ ati dipo ẹyọ kan t i nwọn lu pa.

Ilẹ i gmọ bọ, ara awọn ẹbọra ko gba a ma Awọn Iwin ati Irunmọlẹ lokọkọ bẹrẹ si fi ẹsẹ fẹẹ Sọnpọnna ati Ogun ti o fẹ ṣe oju mida orule ni wọn gba salọ bayi ni Ayunọrunbọ fi ridi awọn ẹni okunkun wọnyi o t u awọn ọmọ Onilogbo s i l ẹ o fun wọn ni ohun jijẹ ati mimu. Ogbọn ori wọn sọkalẹ bi nwọn ti fẹ maa dupẹ lọwọ Ayunọrunbọ. o pọura mọ wọn loju p ẹ l u awọn ẹmẹwa rẹ.



Se'nia s'ejo

Nigbati nwọn b ọ, ninu w a h a l a yi tan, ọkan wọn rẹ wẹsi, Iya ki i ṣe omore ara, ara wọn kọ ọ lati mu irin ajo wọn pọn, wọn fẹnu sọkan pe ki wọn pada sile–ṣugbọn Ige k ọ jalẹ, o ni afi ti nwọn b a jọjọ. Nwọn gba bẹẹ.

Ni kutu hai owurọ ọ j ọ keji, wọn mu irin ajo wọn pọn. Nwọn ko ti r i n ju ibusọ mejila lọ ti wọn f i de ibudo kan Lẹhin bode, na a, ọna kan ya si ọtun ekeji ya si osi, ọna ọtun r wuruwuru, ọna osi si ndan kọrọkọrọ Nwọn j o k o nwọn nwo su u, nwọn koi ti joko to iṣẹju marun ni Eṣu Ọdara yọ lọọkan tin ni.

Inu Ogbojuleogun dun nitoripe ti aba ri ọlọrọ en ori a maa ya Laalu oko oko ki wọn nwọn kii on ati Ogbojuleogun bẹrẹ sn sọrọ nipa ọna t i nwọn yio tọ ninu mejeji ti idamu ki fi ni si.. Esu gba wọn niyaju pe ki nwọn gba apa osi.

Ige ti ise akọbi onilogo ranti ile, oyọ kalamu rẹ okọ iwe kan si awọn ẹbi rẹ. Iwe ra lọ bayi:-

Emi Ige Adubi Ẹlẹsaoku arẹmọ Ọba atijọ Onilogbo lo kọwe yi si nyin nigbati a de Grita Iku ati Iye, ki oma ya nyin lẹnu pe ati ọjẹ ti a ti kuro ni Ile Akoi ti de Ọrun Alakeji.

Idamu ti ari loju ọna ko ṣe fẹnu sọ, afi ki a d a k ẹ Ọpẹ lọ pẹ Ọlọrun ati Ayunorunbọ ti ongba wa silẹ nigbati aba b ọ si idẹkun awọn Iwin buburu ati Alujanu. Eyiti ati nbabọ ere lasan, ni Nisisiyi ni ata t ẹrẹ Irin ajo gan. Ti Edumare ba sọ pe ki riri ku' odara o ṣugbọn adura mi nipe ki Olodumare mo se eyi ni arimọ. Gbogbo awọn aburo mi ni o ki nyi paapa julọ Ogbojuleogun

Nko le sai yọ fun nyin Ọlọrun fi ọmọ kekere iojolo kan ta Ogbojuleogun lore lọna ajo wa Ọmọ Ọba'birin lobi Ọmọ na fun asi kọ ni ila Baba wa akii si mọ, ti ẹjẹ barun kan ara wọn ole wa sile ẹgbaa tọwọ tẹsẹ Ọmọ Ọba ni sei

Odigba kan na ipade wa yio dun bi oyin o.

Emi ni tiyin nitotọ
Ige Onilogbo

Eṣu Ọdara laalu okiri oko-A-bẹni-wa – ọran- bi ako ri da, fi iwe jisẹ, inu gbogbo Ilu dun lati gburo wọn bi otilẹ jẹpe iya nọ fun wọn li ọna Ajiran: Nwọn si tuu ran Esu pe ki o jisẹ fun wọn pe alafia ni awọn paapa wa, ko si ogun, ko si ọtẹ, atipe adura awọn ni pe alọ adara, abọ asun wọn, Esu pada wa jisẹ fun wọn. Nigbati nwọn gburo ile inu wọn dun,

Lẹhin wakati diẹ ti Esu ti jiṣẹ fun wọn, Ogbojuleogun dahun o sọ bayi pe ẹnyin ara, ilẹ nsu lọ, alujannu ni o nsun ikorita ti Ọlọrun ba nsọ enia, enia a ma sọ ara rẹ pẹlu, ibiti a joko si yi, ki ẹ tẹti ki ẹ g b ọ ipade awọn irunmọlẹ ni. Ti nwọn ba si ba wa p a d e lalẹ oni gbẹgẹdẹ yio gbina. Nipa biba ara wọn jiyan ilẹ su wọn sibẹ, okunkun su biribiri nwọn ko si riran rara. Ijaiya de ba wọn.

Ni dede ago kan oru ni Ebọra Anikandajẹ yọ lọkan Ige kọkọ ri i ijimu wọn, ati sọrọ diṣẹ, nwọn kole g b e apa, wọn le gbe ẹsẹ ati sare diṣẹ,

Nigbati Ẹbọra yi ku saaja diẹ ko de ọdọ wọn, orun ara enia bu luu ti i, o duro lojijioni Ẹbọra ni tabi enia? ko si ẹniti o le dahun, nitoripe ninu gbogbo ẹbọra inu igbo, ko si eyiti o lẹru lara bi ti Ẹbọra yi, ogun to ẹsẹ meje, apakan, ẹ s ẹ kan ni o ni, ẹsẹ rẹ to ti Erin, ibiti o ba g b a kọja, ibẹ ni lati di koto, Oju kan ni owa ni iwaju rẹ ipenpeju rẹ si bo o mọlẹ, o n y ọ fintinfintin, o gbe kumọ lọwọ opọn bi ẹrẹ ẹnyin, ko si gende to le gba ikan duro. Eyi mu ki ẹru ma a ba ẹnikẹni ti o ba ba a pade. Awọn tile nsa fun un kẹkẹ pa, nwọn ngbọn titi, nwọn nwa ọna lati sa asala fun ẹmi wọn wọn, ṣugbọn aye ko si,

Nwọn ko dahun, inu wa Ẹbọra yi, o ni ẹ n y i n b u b u r u yi. ẹnyin enia

E Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ Ki ẹ Si Ma a Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ Pẹlu

# IWE SI OLOTU

## Mushin Nfẹ Atunșe

Ẹ jọwọ Olotu, ẹ gba mi ni aye ninu Iwe nyin Irohin Imọlẹ lati kesi Ijọba Ibilẹ Mushin (Mushin District Council) pe a nfẹ atunșe lọpọlọpọ.

Gbogbo awọn titi Mushin ni ko dara to, paapa yanmuyanmu ko jẹki awọn olugbe ibẹ gbadun nitoripe gbogbo gọta lo ti kun. ti ko si si ẹniti yio fọ, ẹ jọwọ ẹ ba wa tun ilu Mushin ati gbogbo titi șe paapa titi Agege Motor Road, nitori titi yi mu idojuti fun ilu Mushin paapa Najiiria ni apapọ.

Ẹ jọwọ, ẹ fi ori kori ki ẹfi kun lukun, ki ẹ fi ti Mushin si ero.

Emi ni,
Modupẹ Adeniji,
MUSHIN

## Igbo-Ọra Nfẹ Omi-Erọ

Olotu. inu mi yio dun pupọ ti ẹ ba le gba mi lati kesi Ijọba rere ti Ipinlẹ Iwọ Orun Orun ki nwọn o fun ilu Igbo-ọra ni omi ẹrọ, nitori omi yi njẹ wa niya, omi kanga ati adagun omi ni awọn ara ilu mu omi yi si nfa ọpọlọpọ aisan ojiji si ilu, gẹgẹbi ẹyin Ijọba ti sọ pe omi daa da ni o yẹ ki a ma mu, o yẹ ki ẹ tete șe eto ki omi de ilu yi.

Nitoripe awọn ara ilu yi ki nfi owo ori jafara rara ki Ijọba si tun jọwọ ki o fun ilu yi ni awọn nkan idagbasoke ilu, a si dupẹ pupọ bi e ba tete ba wa șe awọn nkan ti a nfẹ yi.

Olotu, ẹ șehun, iwaju ni ọpa ẹbiti yin yio ma re si o.

Emi ni,
Sikiru Akintunde,
IGBO-ORA,

## E Tun AgbẹỌla Șe

Nba dupẹ bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le ba mi tẹ iwe kekere yi șinuiwe Irohin Imọlẹ ti o jade lojojumo lati kesi Ijọba Ipinlẹ Ariwa pe, ki nwọn jọwọ ran wa lọwọ lati tete ba wa tun ilu wa șe ni asiko ti gbogbo ilu nwa ilọsiwaju wọn.

Gbogbo oju ọna Agbẹ-Ọla ko dara mọ rara gbogbo rẹ ni o ti bajẹ kọja titun șe agbara kaka ni enia fi le ngun kẹkẹ Ologere loju awọn ọna na ti enia ba ti sọ lori kẹkẹ Ologere nșe ni oluware yio mọ gbin jinnijinni bi ẹsin oniwolimọ

A nbẹ Ijọba rere na ki wọn ran wa lọwọ lati ba wa tun ilu wa yi șe o jẹ itiju fun awọn ọmọ wa to wa ni idale ti nwọn ba wa sile paapa ti nwọn ba mu ọrẹ wọn lọwọ lati wa lo isinmi ni olu wa

Inu wa yio dun ti Ijọba rere na bale tan wa lọrun gegebi nkan ti a nfẹ ninu ilu wa.

Bi o ba dabi irọ, ki awọn Alakoso Ijọba Ipinle Ariwa na tilẹ lọ șe ibẹwo de ilu wa ki awọn na ri wahala ti a nșe Ẹku iṣẹ Olotu mo tun ki awọn alabasișẹpọ nyin pe nwọn șe o

Emi ni
K. A. Owolarafẹ
AGBẸ-ỌLA

## Itan Ilu Ọyọ Nkọ:

Olotu Jọwọ gba mi aye rapẹ ninu iwe Irohin rẹ Imọlẹ lati bẹ awọn Agbagba ilu Ọyọ ti o mọ itan lati kọ itan ilu Ọyọ fun wa ka ninu Irohin Imọle

Nitori a ti ma ri awọn ilu yoku ka, nitorina mo kesi awọn opitan ilu Ọyọ lati ba wa șe eto ati kọ itan ilu Ọyọ nitori ko yẹ ki awa ọdọ mọ itan ilu wa rara ẹnyin baba wa na ni o ma npa lowe wipe "bi ọmọ ko gbọ itan a gbọ arọba, nitori idi eyi a bẹ yin ẹ ba wa tete kọ itan na ki a wa na le tun ma kọ awọn itan ti o mbọ lẹhin.

Olotu, ẹ seun aye ti ẹ gba mi Iwaju ni ẹ o ma lọ, ẹ ko ni rẹhin lailai

Emi ni
Oladunni Ọrẹlaja
IJẸBU—ODE


## Egbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ egbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹrinla oșu yi (14/6/94) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Lagos.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ ki ẹși tete de.

LATEEF BABALOLA
Akọwe Agba



# EGBOGI JẸDIJEDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan ọke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe șe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati șe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn maa powo wọn fun iwosan rẹ șugbọn boya la leri mẹwa ninu awọn ogun o le șe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Șubbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun obẹrẹ akana. Orișirisi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mẹ șe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Șuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orișirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba șe igbọnsẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani șeșẹ wa idi rẹ kio si panwo oriși mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata gboro Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji

ATI NI AWỌN ȘOBU IBADAN:—
IȘẸ LODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA



# MODUPE PRINTNG PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgbose Street,
Phone 21985, Lagos.

# Lebanon Ta Awọn Musulumi L'ọrẹ

Kẹnkẹ sọlẹ ni gbogun nla Mapo Ibadan ni ọjọ aba mẹta ti se ọjọ kẹrindinlogun oṣu kẹrin odun yi nigbati ijọba orilede Lebanon fi egba (2000) iwe ede Arabic ta gbogbo awọn musulumi Iwọ Orun lọrẹ fun itẹsiwaju ẹkọ awọn ile iwe gbogbo ti o nkọ ede na ni iplnlẹ Iwọ orun

Alhaji L. A. Salami alaga ile ẹjọ ibilẹ kan ni Ibadan ti o ṣe aseyẹ na tọkasi ninu ọrẹ rẹ pe, itọrẹ mejeji yi jẹ ifihan ifẹ nlanla ti orilẹ ede Nigeria

Asoju ile Lẹbanou ni ile ni enia, Slaman Ferah ti o gbe iwe na fun Alakoso Ijọba Iwọ Orun kan ọgbẹni Ayọ Ajibọla sọ ninu ọrọ tirẹ pe on ati Ijọba li Lebanon dupẹ lọwọ alakoso eto ẹkọ ati Ijọba iwọ orun ti o ni ifẹ lati gba awọn ọmọ ile iwe ni ipinlẹ Iwọ orun laye lati ma kọ ede Arabic osi se ileri ninu ọrọ rẹ pe Ijọba orilẹ ede Lebanon si yio fa sẹhin lati maa sa ipa wọn nipa idagba soke eto ẹkọ ni orilẹ ede yi

Ogbẹni Ayọ Ajibọla Alakoso kan ninu ileṣẹ eto Ijọba iwọ orun ti o jẹ alaga ase yẹ na sọ ninu ọrọ tirẹ nwọn dupe lọwọ Ijọba orile-ede Lebanon fun iru ipa nlanla ti nwọn ti bẹrẹ si ni ko ninu idagba soke eto ẹkọ ni orilẹ edeNiagiria ati ni iwọ Orun lakotan osi se ileri pe Ijọba on yio ṣa ipa rẹ lati ri pe wọn lo awọn anfani na ni ọna ti yio fun wọn ni iwuri,

Ogunlọgọ awọn Musulumi ni obirin ati okurin ni o wa si ibi ẹyẹ na diẹ ninu wọn ni Alhaji Y. S. Isọla Abdul Ritha Elelhein ọjọbgọn fun Arabic ni ile ẹkọ giga Unifasiti Ibadan. Ghassan Khaled ọjọgbọnfun ẹkọ Arabic ni Universit Kano Ọlọla Ogunmuyiwa Alhaji Muhlo Immamu ti Mọsalasi nla Ibadan Alhaja Humbani Alaga Alhan Adijanu Balogun Alhaja Hja Dada Ogbẹni R. A Balog.T Alhaji Agbaje ati Hizbu I Lun Algaib pẹlu awọn jankanjan kan miran

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan. 22-Feb20) Ọ k a n rẹ kun fun idamu, akoko to lati wadi ohun ti o fa a, ṣe suru ki o jẹki nwọn pari ọrọ ija kan ti o ti mbẹ nilẹ.

PISCES (Feb 21-March 20) Tete ba ọrẹ rẹ Obinrin kan sere ko ni gbagbe, nigbana ohun ti o mba ọ lẹru yio fo lọ.

ARIES (March 21-April 20) Maṣe gbe gbogbo iṣẹ sọdọ alejo kan, alejo na le jẹ eyiti yio fa ibinu wa fun ọ nitorina ki o sora rẹ lasalẹ ọjọ oni.

TAURUS (April 21-May20) Mu owu jijẹ ati aini gbẹkẹle kuro ninu ọrọ rẹ, Isọra mbẹ fun ọ loni nibi iyan jija pẹlu ẹnikan.

GEMINI (May 21-June 21) Maṣe gbagbe ohun ti o njẹ ti o fi ori alafia, iranti yio jẹki ogbayi loni yio si jẹki o dopin oke isoro rẹ.

CANCER (June 22-July 22) Maṣe tẹ irin meji bọ ina nigba kan nitoripe ọkọkan ni a nyọ ẹsẹ kuro ẹkɪ maṣe fi ara rẹ wu ewu, ki o si fi suru si. Ẹgbẹ to dara ni awọn ti o fẹ ba rin ni ọjọrọ dara, ṣugbọn fi ori ti

LEO (July 23-Aug.22) Ore t i o ba ṣe ko ni si ibanujẹ.

VIRCO (Aug, 23-Sept. 23) Enikan ti o feran rẹ le ni imọ nipa ohun ti o fẹ, saṣe pẹlẹpẹlẹ' ẹsọ di ọwọ re

LIBRA (Sept. 24-Oct. 23) Gbogbo irin si rẹ gbo gbo lojẹ ire ati alafia, nitoripe o mọ owo nina daradara awọn ọjulumọ titun, le ṣe ọ ni anfani.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Maṣe lera pe ọti mi mu yio ṣe ọ ni anfani, rara o, ṣọra lalẹ oni, ki o ma ba jẹ egbogi, ki gbogbo ara ma ba ma ro ọ.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec21) Ire pọ fun ọ loni alafia to mi bẹ fun ọ yio jẹki o le kọju ija si isọra to mbọ

CAPRICORN (Dec 22-Jan 21) Gbogbo a w ọ n obinrin yio ma wọ ti ọ ninu oṣu yi ṣugbọn ṣọra maṣe ẹ ran tutu pupo


## CLASSIFIED ADVT

"KIU FUNG MANUFACTORY BOX 3812, HONGKONG, IMITATION JEWELLERY WIRE HOOKS"

BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi oriṣiriṣi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO POKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

Dan wo ni lẹhẹnsoso lo ri iyato

## Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin Ayọ De

Bere Ojulowo Egbogi awon Faranse gidi ti a npe ni **'CORSIVER'A**



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a ṣe ni pataki Fun „ARỌN KINIṢA" tabi LATANATAN" ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹrahu tabi lati ma ṣe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba i lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ẹhin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige tabi sisan ba nyọ ọ lẹnu ..... bere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo ṣe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn amodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi na njẹ ni ṣọbu awọn.

Waterloo Stores
8, Palm Church Street; Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji Lagos.)

ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.

# Ilo Ahọn Larin Wa

## Lati Ọwọ S. O. Jaiye, Eko

Bi mo ti mo nronu lori awọn ẹya ara ni mo wa bẹrẹ si yẹ awọn ara wọn yi wo ni mo wa bẹrẹ si fi ọwọ kan ahọn lẹnu mi Mo mu awojiji lọwọ ni mo bẹrẹ si wo ahọn mi ti mo si nwo bi mo ti yi kakiri larin awọn opo ẹhin to yi ka kiki O ri rebete o si jẹ ẹran to fẹlẹ ti kosi ni egun.

Ni salẹ ahọn ni eran tẹ rẹ kan to dabi ẹnipe oso mọ le O si yọ jade l a r i n ẹhin. Bayi ni mo bere lọwọ ara mi pe kin ile ara re bete yi?



Ọgbẹni S. O. Jaiye

Ahọn jẹ ọkan pataki larin awọn ẹya ara to wulo pupọ Laisi ilo ahọn ninu ara wa ati sọrọ tabi ati ara wa sọrọ yo jẹ isoro pupọ. Orin di·dun ti a nkọ ti a ngbẹ ninu ode aiye ki ba ṣe gbọ-ọrọ alaye ti a nba wa sọ ki iba wa rara.

Asọve ati iba ni ṣe apero ki ba si fun wa mọ. Laisi ilo ahọn ati jẹun ko ni si rara.

Ahọn mu ki onjẹ wa se jẹ ati ohun gbogbo ti anjẹ ahọn jẹ iranlọwọ ninu iṣẹ na

AHỌN LILO

Ọpọ ohun rere ti ọmọ enia fọ ara rẹ lọwọ a i y e nwa nipa ahọn. Lilo ahọn bi o ti yẹ ija ati asọ a ma wa si arin ile.

Bi ọkọ ko ba mọ ilo ahọn to dara ko le gbadun ile rẹ. Bakanna aiya ti ko ba mọ ilo ahọn ija ojojumọ ni yo ma wa si inu ile wọn.

Ẹnikẹni to ba mo ọrọ sọ a wipe o mọ ilo ahọn ni. Ilo ahọn si ọna odi a ma fa ija ati ogun wọ ilu,

Aimọ ilo ahọn ọrọ Ọlọrun tilẹ sọ pe bi ẹnikan ba ro pe on nsin Ọlọrun ti ko ba le ko ara rẹ ni ijanu ṣugbọn ti o ntan ọkan ara rẹ.

Isin oluwarẹ asan ni. Bi ẹnikan ba wa ninu aiye ti a ko ba ri aṣiṣe rẹ. Ki a mọ wipe ẹni na ko ara rẹ ni janu ninu ilo ahọn.

Ani ọrọ Ọlọrun tun jẹri si pe ahọn jẹ ina aiye eṣẹ larin awọn eya ara wa. Eyi to nti ina bọ ipa aiye wa· Asẹhinwa asẹhinbọ ọ r u n apadi atina bọ on na.

Larin awọn agba ko si ibiti ahọn ko le dasilẹ, Bakanna larin awọn ọmọde ilo ahọn nmu aisinmi wa si arin wọn. Eyiti o ma mu wahala ba awọn obi f u n aisinmi.

Ahọn to yẹ julọ lode wa oni nipe ki a ko ara ni ilo ahọn bakanna ni ti a ba nlo ahọn wa rere a w ọ n ọmọ wa yo kọ ẹkọ ninu iwa ilo ahọn wa.

Awa Yoruba ninu ọgbọn wọn sọ pe ọrọ rere yọ obi lapo ṣugbọn ọrọ lile yọ ọfa ninu apo. Eyi ni pe ọrọ pẹlẹ yi ibinu pada bi ọrọ lile ti nru ija soke,

Nipari ọrọ mi yi o yẹ ki aṣe akiyesi pe gbogbo awọn olokiki aiye wa nipa lilo wọn rere. Nitorina o yẹ ki gbogbo wa ko mọ bi ati nlo ahọn wa.

O digba diẹ o!


# MODUPE PRINTNG PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* M O D U P E P R E S S *Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 – Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street,**

Phone 21985, Lagos.



# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn n gba po-owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu awọn ogun o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣubbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun obẹrẹ akana. Orịṣiriṣi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ewẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orịṣiriṣi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnsẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣẹ wa idi rẹ kio si panwo orịṣi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata gboro Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji

ATI NI AWỌN ṢOBU IBADAN:—
IṢẸ LODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 716 WEDNESDAY, JUNE 10, 1964 (2D)

## Folefole Wewon Olosa Odun Kan Meta

IBADAN:— Oro ko wo ni ile ejo kekere Ibadan nigbati awon Olopa mu Odaran kan, Lewis Uzoma wa siwaju adajo ni ojo Aje ti ise ojo kejo osu yi fun esun ole jija ati ile fifo.

Ogbeni Adeneekan Ademola, okan ni nu awon agbejoro pataki ni ilu Ibadan ti o ba odaran na sejo se alaye fun ile ejo pe, ki on to sun funtara on ni on ti ilekun ati ferese ile on gbonin-gbonin sugbon nigbati on ji ni owuro ojo keji ni on ri ferese ati ilekun oju ona ti nwon si sile nigbati on si se akiyesi awon ferese da on ri pe awon irin to wa loju ferese nwon ti ge gbogbo re lo ibiti on gbe se akiyesi yi lowo ni on bo ju wo ile ni on ri pe ero asoromagbesi alamoran (Telivision) ati awon aga ijoko meje ni awon olosa ti ji gbe lo lesekese ni mo si fi oran na lo sun awon Olopa ni Tesan.

Okan ninu awon Olopa Ijoba Ibile Ibadan, Ogbeni Fatai Alonge nse alaye fun ile ejo pe bi Ogbeni Ademola ti so oro na fun awon tan ni awon ba bere si wa awon eru na kakiri, ko pe pupo ti awon ri eru na ni ile Odaran ti nwon mu wa yi ni awon ba mu Odaran na wa si ile ejo pe, ki o wa so fun adajo bi eru eleru ti de ile re.

Nigbati Odaran na rojo, ti o si gba pe on jebi, ni adajo ba so pe ki o lo fi ewon odun meta jura.

# IJOBA MBA ENAHORO SEJO

EKO:— Gbogbo enia to wa ninu ile ejo gigajulo ti Eko lo nmi ori nigbati agbejoro Ijoba Ogbeni Yaya Jinadu ati adele adajo agba Olola Daddy Oyeoma nfa oro mo ara won lenu lori oro ti Oloye Enahoro igbakeji olori egbe Afenifere Ohun ti o fa fifa oro mo ara eni ni lenu ofin kan ti o so pe lehin Osu mejila ti nwon se idajo tan nilu Oyinbo ati agbegbe re enikan ko ni anfani ati tun wa bere owo itanran tabi irinse.

Alakoso eto Ofin fun Apapo Ijoba lo pe Oloye Anthony E. Enahoro lejo siwaju adajo agba fun ilu Eko pe, ki o fi ase si ki Apapo Ijoba le gba ponun merindinlogbon le ni irinwo sile mesan ati kobo mefa (£426 : 9s : 6d) eyiti ise owo ti ile ejo ilu Oynibo palase pe ki awon gba lowo Oloye E nahoro nigbati o fi jebi ejo ti o pe ni ilu Oyinbo.

Ni iduntu ni Apapo Ijoba nwa Oloye Anthony



OLOYE ANTHONY ENAHORO

Enahoro lati so ti enu re ninu ejo idite si Ijoba ati pe, o wa ninu awon ti o fe doju ijoba bole. Bi Oloye na ti de ilu Oyinbo ni owo ba te ni o ba npe ejo ti o si njebi ase-hinwa-asehinbo, Ile-ejo ni Londonu ni ki Oloye Enahoro wa sile.

Nigbati nwon pe ejo na ni ijeta, agbejoro Ijoba so pe, ki ile ejo fun awon lase lati gba owo ti awon na le Oloye Enahoro lori nigbati o fi wa nilu oyinbo.

Adajo so pe, Ijoba ti pe ki o to gba ase lati gba owo ti Ijoba na lori oloye na nilu oyinbo, nitoripe iwe ofin so pe, lehin osu mejila ti enia ko ba se gba ose ati gba owo ti ile ejo da, oti bo sodi.

Agbejoro so wipe nit to ni osu kinni odun ti o koja ni adajo se idajo sugbon lati osu kerin odun ti o koja ni awon ti o nseto owo ti enia ba na lori ejo ti bere si se eto na, ti awon si gba iwe eri owo na ninu osu kejo odun yi.

Adajo so pe, lati osu kini odun tio koja kini e nwo? Ohun ti e le se nipe, ki e toro aye gigun nitoripe asiko ti koja ki eto wa pejo owo na,

Lehin orisirisi oro ti adajo ati agbejoro Apapo Ijoba fi ngbe oro won lese ni adajo ba fun agbejoro Ijoba laye ose kan lati wa so idi ti aye kofi koja ki nwon to wa pejo owo ati bi aye basikoja kini alaye re ti o le se.

Adajo ba sun gbigbo ejo na si ojo Eti ti ise ojo kejila osu yi.

## Ikomo Jade Okunlola Larinrin

EBUTE-METTA:— Irohin ko to afojuba ni inawo ikomo jade ti Ogbeni Tijani Okunlola ati iyawo Iyaafin Rabi Idowu Okunlola se ninu ile won ni nomba 2, Olayinka Street, Ebute-Metta. Inawo na ko yoyo a fi eniti o ba de ibe ni o le fi enu rohin. Bi awon enia ti nde lati Mushin bena ni awon ara Eko, Shomolu, Apapa ati Agege pelu. Ni ojo etadinlogbon osu to lo.

Bi o ti di agogo mejo owuro Ojo na ni Alufa Busari Adegbenro ti de, ti o si bere sin isomo loruko na ni ona ti Imole awon enia ti otun wa pelu alufa na ni, awon Ogbeni S. Ade. Oladeji L. Ader ninu Alaga, B. Adegbola G. Olaore ati ri Adebayo. Omo Obinrin ko tile ni oniia Nwon si so Omo na ni Tajadeen.

Alufa na si fi enu kan die ninu iwa Ogbeni Okunlola ati iyaafin re bi nwon ti se mura si esin Musilumi si o si wa so fun gbogbo awon enia pe, ki nwon ko iwa lati mo rin Olorun lara won,

Awon egbe Oke-Amu Fed. Union nse ni ojo na awon bi T. Okunlola, Alaga egbe won L Aderounmu, K Omotosho, Y Kehinde S Ogungbade L A Ayadeji; T Oketunde. S Ade Oladeji ,ati akowe L T Oladeji Die ninu awon omo egbe to wa niyi, Egbe Oke-Amu, Irepodun Obanibashiri, Oluwanigbeniga Baptist Members, Ike-Oluwa ati beebe lo. Bena ni awon enia lati ile-ise Okunlola awon Ogbeni Babatunde Akawuyo Atanda, Raimi Baba Kudi.

Babatunde dupe lowo Okunlola pe oku inawo na Oluwa yio wo omo atipe gbogbo awon omo Iseyin baa yo pelu,

Ogbeni Okunlola fi jije ati mimu te awon enia na lorun, beni awon Onilu egbe Ife Lodun Otu bere si korin pe "Okunlola lo nbe lode eru ko le 'bo wa o",

Ti awon egbe Obinriu si njo ajo wole bi kokoro die ninu awon Obinriu to wa niyi Alaga egbe Obinrin Funmani Adebayo. Iyaafin Rabi Okunlola Sifatu Abeni, Suwebatu Olodeji, Sauratu Oketunde.

Oluwa yi ba ni wo omo na o, Amin,

Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamigbose Street Lagos Phone:- 21985
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos (10/6/64)